# “Mumini ti o pe jù ni igbagbọ ni ẹni tí ìwà rẹ dara ju, ẹni tí ó loore ju ninu yin ni ẹni tí o dara ju fun awọn obinrin wọn”

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Mumini ti o pe jù ni igbagbọ ni ẹni tí ìwà rẹ dara ju, ẹni tí ó loore ju ninu yin ni ẹni tí o dara ju fun awọn obinrin wọn”.
[O daa] [Abu Daud ati Tirmiziy ati Ahmad ni wọ́n gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pé èèyàn ti o pe julọ ni igbagbọ ni ẹni tí ìwà rẹ dáa, bíi títú ojú ká, ati ṣíṣe dáadáa, ati ọ̀rọ̀ rere, ati ki èèyàn má fi sùtá kan ẹlòmíràn. Mumini ti o loore julọ ni àwọn ti wọn loore julọ fun awọn obinrin wọn, gẹgẹ bii ìyàwó rẹ, ati awọn ọmọbìnrin rẹ, ati awọn arábìnrin rẹ, ati awọn mọlẹbi rẹ lóbìnrin; torí pé àwọn ni wọn ni ẹtọ si iwa dáadáa ju ninu awọn èèyàn.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee